OWE

Ọgbọn pẹlu Suru la fi nmu Erin wọ inu ilu.

# IROHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

READY FOR SALE
Iwe Arofọ ti -:
ANOYIN LOHUN-BI-ỌMỌGE- IMARO
APA KẸTA
LATI ỌWỌ
G. A. SOWUNMI
Price 2/-
Modupe Press
16 Bamgbose Street,
Postage Extra

VOL. II No. 56 WEDNESDAY JULY 23, — JULY 29 1958 KỌBỌ KAN (1d)

# OKO RELUWE PA OLOKO

Yaba

Irohin kan wa wipe oko ti o nko awon osise Loko, Ebutemetta. Iddo, Iganmu ati Apapa ti o dide lati Ifo lati kutukutu owuro ni o sesi pa okunrin kan ti a npe ni Alabi Ologun ti o ngbe Idi-Oro ti o nsise oko ile (Railway) ni Running Shed Ebute-Metta.

Bi a ti gbọ ti ọrọ na lọ niyi:- Dọkita ti fun Alabi ni iwe wipe ki o lọ fi ara sile nitori aisan ti o mba ja. Nigbati asiko na si par, o wọ ọkọ awọn oṣiṣẹ lati lọ bẹrẹ iṣẹ rẹ ni Running Shed Ebute-Metta.

Lojiji ni a gbọ ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ ti o wa ninu ọkọ pẹlu rẹ fi igbe ta, kia-mọsa ọkọ na ti duro, awọn oṣiṣẹ sare lọ sibẹ lati wo kini ohun ti o ṣẹlẹ.

Nigbati nwọn ri ohun na ti o ṣẹlẹ, ẹlomiran ko duro de ọkọ mọ titi o fi de ibiṣẹ rẹ, awọn elomiran bu si ẹkun nigbati nwọn ri Alabi Ologun ti ọkọ ti ge e si wẹwẹ bi ẹran ileya ni Yaba.

Awọn Ọlọpa ni a gbọ wipe o ko awọn ekiri rẹ na lọ si ile alaisan fun ayẹwo, ọrọ na wa lọwọ awọn Ọlọpa, nwọn nṣe iwadi rẹ lọwọ.

## Tanki Epo gbina ni Apapa

APAPA

A gbọ wipe awọn afami iyẹn ni awọn ti o nfa omi sinu ile fun lilo, ti nwọn nṣiṣẹ nitosi tanki, eyiti epo moto ati Karosini wa ninu rẹ. Nibiti awọn ṣiṣẹ yi ni a gbọ wipe tanki epo Karosini gbina, Ọlọtu iṣẹ epo Mobil Oil sọ pe ori lo yọ awọn ti ko jẹki awọn da ghese rep... nitoripe lagiko ti ina yi ṣẹlẹ, epo ti fẹrẹ tan ninu tanki ti o gbina na.

Nigbati ina na bẹrẹ, ko si panapana ti o le sunmọ ina na, enia ko le fi oju ri ina paapa, ayafi eefi ti o dudu ti o si ṣu bi ojo ti o si bo gbogbo ilẹ gẹrẹjẹ.

Panapana Apapa nikan lo ti mbẹ lẹnu rẹ ri nigbati o ṣe ni awọn ti Eko de ti Yaba papa tun de, awọn si jijọ dawọ bo ina na, ni akọkọ ko si ẹniti o le sunmọ, nigbati nwọn ko simi ti nwọn ko si mọwọ kuro lara rẹ, nwọn bori rẹ ni agogo mẹfa irọlẹ, ki nwọn to le pa ina na fẹrẹ to wakati kan. Atẹgun tun ndigbolu ina na, o si fẹrẹ

(Wo iyoku loju ewe kẹrin)

**Egbe Olorunsogo Trading Company Oro**
GBE MORRIS MINIBUS LC 9740 JADE

Eyi ni awọn ọjọ ti Motor yio ma kuro ni Eko.
MONDAY, WEDNESDAY, FRIDAY
Eyi dẹ ni ọjọ ti yio ma kuro ni Ọtun Oro
TUESDAY, THURSDAY, & SATURDAY
Tẹ ba fẹ wọ Motor yi ni Eko, ẹ lọ si:-
28 Idunmagbo Avenue c/o Mr- Michael O. Awoyale
Motor yi ko gba ju enia mẹtala lọ.
Agogo mẹsan owurọ ni Motor yi yio ma kuro ni Eko ati ni Ọtun Oro pẹlu.
Manager: M. O. AWOYALE

## Awon omo ilewe nilu Oyinbo lo toju kan ibiti a gbe nsike omo



Ninu ile alaisan ti o wa ni ilu Epsom, agbegbe kan nilu Gẹsi ni nwọn ti ṣe afihan fun gbogbo awọn ọdọmọbinrin ilu Oyinbo, orisirisi ọna ti a ngbe ṣe itọju ọmọ ikoko, ki nwọn si le mọ ọ latigba ewe wọn, ki nwọn to di abilekọ. Ninu awọn ọmọ ile ẹkọ ti o duro ti a nwo yi ni a ti le ri ọmọ akẹkọ kan lati ilẹ Naijiria wa, lapa osi, orukọ rẹ ni Fọlaṣhade Oṣunsẹdọ.

Orukọ gbogbo wọn niwọnyi:— o bẹrẹ lati ọwọ osi, M. Rulton, J. Couldrick, S. Mawhood, Padi obinrin B. Mary ti o wa lati Coment, C. Wade, C. William, B. Cooper, ati W. Gorden.

# LAKAYE NI BABA OGBON

O BẸRẸ LATI ỌSẸ TO KOJA

BAYI ni ọgbọn damu tititi o fi pada wa sile lai ri owo tabi aṣọ gba pada. Bi oti de ile, o ko gbogbo itan yi lelẹ ni waju Lakaye bi on ti wahala to ti on ko si tun le mọ ẹniti o ra aṣọ lai sanwo.

Lakaye rerin titi, o si dahun pe eyi ni ọgbọn yio fi mo pe on lakaye mura o fi ọna irin ajo yi pọn o di ilu awọn lekeleke.

Bi o ti debẹ o pe gbogbo wọn jọ o si sọ fun wọn pe on ni oro pataki kan lati bawọn sọ, o ni ọgbọn ki on to tẹnu bọ ọrọ yi on ni lati ri pe ọba wọn wa lori ijoko, nitoriti ọrọ ti o kan gbogbo ilu ni. Lakaye lanu silẹ o si kigbe pẹlu itara pe, "Bawo ni ẹda Ọlọrun ti awọn dara ba wọnyi se ni lati gbe iru ilu ẹlẹwa bayi laini ọba. O wa dahun pe loni yi gan li on yio fi oba jẹ fun wọn, o wa sọ fun wọn pe ki wọn lọ gbe ẹwu nla atata kan wa lati wọọ fun ẹniti yio jọba, nwọn dahun pe awọn koni ẹwu miran ju ti ara awọn yi. Lakaye tun sọ fun wọn pe ki wọn ronu wọn daradara.

Nwọn dahun pe afi ẹnikan ninu awọn li o ni ẹwu nla kan, lakaye si ni ki nwọn lọ pe wa ti on ti ẹwu rẹ ati pe on na gan ni yio jọba, pẹlu itara ni nwọn pe wa ti on ti ẹwu ẹtu ijelo. Lakaye ri pe ẹwu ti ọgbọn lọta ti ko ri owo rẹ gba ni, ṣugbọn bi o ba mu ẹiyẹ yi ni ole, boya inu le bi wọn ki wọn si bẹresi ṣa ni iko nitoripe wọn pọ ju on lọ.

Nigbati ni lakaye tun lo ọgbọn pọ mọ tirẹ, o si sọ fun wọn pe o ku ẹwu irukanna marun ti ao fi wọ awọn oloye marun miran ti yio ma ba ọba yi gunwa gẹgẹbi iwarẹfa mẹfa. Nwọn da lohun pe ko si ẹniti otun ni ẹwu, o wa sọpe ki wọn fun on ni iwọn iba owo onjẹ ki on lọ sodo awọn abunsọ lati hun iru rẹ ati ki nwọn o da ni iru rẹ, o fi kun pe kiki ade ti yio yio ra bọ nikan ni ọba on fi yatọ si wọn ati pe ki nwon ma mura owo silẹ de on.

Eyi mu ki inu awọn ẹiyẹ wọnyi dun lopolopo, nwon si gba lai paa lohun da rara. Bayi ni nwon gbe ẹwu ẹtu fun pelu owo onje lati lose bi oti wi, nwon si nmura.

Lakaye gbe ewu na wale Bi o ti tu ewu yi ti o fi han ọgbon pelu owo onje ti nwon fun, ọgbon nṣe "ha! bawo li o ti rin?" Lakaye wa dahun pe se on ti wi tẹlẹ pe on Lakaye ni baba Ọgbọn.

Lati Ọwọ—
SUNMỌNU ALAO

Itan yi si ko wa pe ti a ba bi ọmọ ti o ni ogbon lai ko si Lakaye, adanu obi ọmọ ni eleyi wa fun. Otun ko wa pe bi eni ba lọgbọn ki o gbiyanju lati ma lo Lakaye ni awọn Oyinbo npe ni 'iPractical Common Sense" Bi ọgbọn ba so eso, Lakaye ni mọ kika rẹ ati ibiti yio wọ si,


## Iyanju fun Okunrin ati Obinrin nipa oro IFE

Ọpọlọpọ ninu nyin ni o ti nka ninu awọn iwe Irohin Oyinbo ti a npe ni DRUM ati Daily Service nipa ọdọmọkunrin ati ọdọmọbinrin nipa darudapọ ti o wa ninu ọkọ fifẹ ati iyawo fifẹ ati ọna ti wọn le fi gba ma yanju edeaiyede ti o ba wa larin ara wọn—Eyi mu ki awa IROHIN IMỌLẸ papa fi aye silẹ ninu Iwe Irohin wa oloyinmọmọ lati ma gba awọn olukawe wa ni iyanju pelu, nitorina o le bere nkan ti o ba ru ọ loju nipa ọrọ IFẸ (Marriage & Love Affairs). Kọwe Miss Bọsẹde Olufunmilayọ. 8, Ojo Road Oduabọrẹ Mushin.


## Idahun Si Ibere S. Adigun

TARKWA GHANA

EKINI:— Njẹ o ba dara ki obinrin ma yan ALE fun ọkọ rẹ?

IDAHUN:-Ki iṣe ohun ti o dara ki obinrin ma yan ale obinrin ẹgbẹ rẹ fun ọkọ rẹ, o ye ki oko papa ni ọgbọn lori pe, on nkọ iyawo on ni paṣanga niyen, nitoripe ọrẹ re ti o fa fun oko tirẹ lati ba lo po, ka pa oro yi ti, pansaga lodi si ofin Oluwa ati t'eda papa nitoripe Oluwa so pe Iwọ ko gbodo ṣoju kokoro si aya eni keji re, Iwo ko si gbodo ṣe panṣaga pelu.

EKEJI:- Kiniṣe ti ọkọ ba nyan iyawo oniyawọ ni ale ti iyawo rẹ si mo - ti iyawo papa ba si gbe igba aṣẹwo ti oko fii nlodi si.

IDAHUN:—Ni kukuru ohun ti mo fe ki o ye o ni pe iwo ko gbodo ṣe pansaga gege bi ofin Oluwa, ti o ba nyan ale ti o ba si je mimo fun iyawo re, ti obinrin papa si nṣẹwo, ẹṣẹ na wa lorun rẹ, nitoripe iwo lo fi ona han an. Ko jẹbi rara.

Emi ni:—
BOSẸDE OLUFUNMILAYO
8, Ojo Road Oduabọrẹ,
MUSHIN.

## Awon to lo kose nilu Oyinbo lo be ile ti ati nhun Asọ wo.



EGBE awọn obinrin ti o lọ ko iṣẹ nilu Oyinbo da kan lọ wo ile iṣẹ ibiti a ti nhun aṣọ PIRINTI ni Manchester. Nigbati nwọn de ile ibiti nwọn ti nhun aṣọ nibe ni wọn ti ba ojulumọ kan pade ti o mo ọkan ninu awọn obinrin na tile-tile. Ọrọ ti nwọn sọ ti o dunmọ Olotu ile ihunsọ na ni wipe, awọn nfẹ ki nwọn ma hun aṣọ ti o dara wa silẹ Nijiria. Nigbana ni nwọn mu awọn obinrin na lọ sibiti nwọn ti nrẹ aṣọ laro lati fi hun pe, bi o ti le wu ki orun ilẹ Najiria muto, awọn aṣọ na ko ni ṣa.

